# ÌKÚN -- OMI

### Gęnęsisi 6:14-22; 7:1-24; 8:1-22

### ĘKỌ 6 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Iwọ wá, ati gbogbo awọn ara ile rẹ sinu ọkọ̀" (Gęnęsisi 7:1).**

**Bi Ọlọrun ti Wi**

Ikún-omi dé, gęgę bi Ọlọrun ti kilọ. A ṣi awọn ferese Ọrun silę ojò si bęrę si i rọ̀. Fun ogoji ọ̀sán ati fun ogoji òru ni ojo fi rọ̀. Isun ibu nla ya, omi si kun gbogbo ilę. Iru ikún-omi bęę ko i ti i ṣęlę ri ṣaaju akoko yii.

O ha ṣe e ṣe fun eniyan kankan tabi ęranko kankan lati wà laaye ninu ikun-omi bęę? Ęnikęni tabi ohunkohun ha le là? Bęę ni, àbá ati là kuro ninu ikun-omi naa wà. Ninu gbogbo awọn eniyan, ęyọ ọkunrin kan pere ati awọn ara ile rẹ̀ ni a gbala. Ninu gbogbo awọn ęranko, ayafi awọn ti o wà ninu ọkọ̀ ni a kò parun. Eniyan kan wà ti Ọlọrun le fi ọkàn tán, ęni ti i ṣe olododo ti o si bá Ọlọrun rin. Fun ọkunrin kan yii, Noa, ni Ọlọrun ti fi ipinnu Rẹ̀ hàn.

**Iwa Buburu**

Ọlọrun ti wi pe ikun-omi yoo ṣęlę to bęę ti yoo fi pa "ati enia, ati ęranko, ati ohun ti nrakò, ati ęiyę oju-ọrun" run. A rán eyi fun ijiya ati idajọ fun ẹ̀ṣẹ. Awọn eniyan naa buru to bęę ti o fi dun Ọlọrun pe Oun ti dá wọn rara. Ọlọrun ri inu ọkàn eniyan pe iro ọkàn wọn "kiki ibi ni lojojumọ." Ilę aye kun fun ibajẹ, eniyan ko si ronu nipa Ọlọrun ati ọna Rẹ̀. Ọlọrun korira ẹ̀ṣẹ o si yę lati pa awọn ti n dęṣę run.

**Ọna Abayọ**

Ọlọrun ti fun Noa ni awọn itọni kan lati tęle ki o ma ba le ṣegbe pęlu awọn iyoku nigba ti ikun-omi ba de. O mu ki Noa mura silę de ikun-omi naa nipa kikan ọkọ kan. O dabi ọkọ oju-omi ti ko ni itọkọ, àjẹ̀, ęrọ tabi igbokun ọkọ. Igi ni a fi ṣe ọkọ naa pęlu ọ̀da lode ati ninu ki omi ma ba le sun wọ inu rẹ̀, ipele męta ni ọkọ yii ni, pęlu ferese kan ati ilękun kan. Ọlọrun sọ pato fun Noa bi yoo ti ṣe kan an. "Bę̃ni Noa si ṣe; gęgę bi gbogbo eyiti Ọlọrun palaṣę fun u, bęli o ṣe." Noa gbọran si Ọlọrun, a si da a si ni akoko ikun-omi naa. O kan ọkọ naa gęgę bi eto Ọlọrun. Ko paarọ titobi rẹ̀, iru igi ti i ba lo, iye ipele rẹ̀, iye ilękun ati ferese tabi ohun kankan nipa rẹ̀.

**Gbęnagbęna**

Awọn ọmọle lode oni maa n tęle apęęrę tabi aworan. Nigba miiran lęyin ti a ba ti bęrę kikọ ile tabi ọkọ̀ a maa n ṣe iyipada. Nigba pupọ a n fi nnkan kan kun un tabi ki a yọ nnkan kan kuro. Ọpọlọpọ igba nigba ti ile naa ba pari ni ki i jọ aworan naa gan an. Aini ohun elo to, aṣiṣe kan, tabi igbero tabi ifę ęni kan le mu ki ile yii ma jọ aworan rẹ̀ bi a ti ya a silę.

**Ile**

A le pe olukuluku eniyan lonii ni ọmọle nitori o n kọle fun ayeraye. Ọlọrun ti fi eto igbala lelę. Ki eniyan ba le là o ni lati tęle eto Ọlọrun. Gęgę bi Noa ti ṣe ohun gbogbo ti Ọlọrun palaṣę, bęę naa ni a ni lati ṣe ohun gbogbo nisisiyii gęgę bi eto Ọlọrun, eyi ti o wà ninu Bibeli.

Iṣę nla ni o wà niwaju Noa lati ṣe. Ki i ṣe ohun ti o rọrun lati kan ọkọ naa, ṣugbọn Noa kan an, nitori Ọlọrun ni O paṣę fun un lati kàn án. Bi o tilę ję pe o gba iṣę lile fun ọpọ ọdun, Noa ṣe gęgę bi Ọlọrun ti palaṣę. Ọlọrun ki i beere ohun ti ko le ṣe e ṣe lọwọ eniyan.

Noa ję "oniwasu ododo" (2 Peteru 2:5). O ṣe e ṣe ki awọn eniyan beere lọwọ Noa ohun ti o n kọ́ ati eredi ti o fi n kọ ọ. Lai ṣe aniani awọn miiran le fun un ni imọran. Boya awọn miran fi Noa ṣẹ̀sín, wọn ko si gba ohun ti o wi gbọ́. Noa ko ni ṣai ti waasu fun gbogbo wọn, ki o si sọ ti ikun-omi ti n bọ̀ wa. Ṣugbọn kiki Noa ati ębi rẹ̀ ni o gba ọrọ Oluwa gbọ́ ti wọn si mura silę lati sá kuro ninu idajọ ti n bọ̀.

**Lonii**

Awọn eniyan wà lonii ti wọn gba Bibeli, Ọrọ Ọlọrun gbọ́. A kà nipa akoko wahala ninu eyi ti Ọlọrun yoo yọ awọn eniyan Rẹ̀ kuro – "ani gbogbo awọn ti a ti kọ orukọ wọn sinu iwe" (Danięli 12:1). A ka nipa ọjọ idajọ kan ti a sọ nipa rẹ̀ pe: "olukuluku wa ni yio jihin ara rẹ̀ fun Ọlọrun" (Romu 14:12). Bibeli kọ́ ni pe awọn ti n dęṣę ki i ṣe eniyan Ọlọrun, nitori "ęnikęni ti o ba ndęṣę, on li ẹrú ẹ̀ṣẹ" (Johannu 8:34). A ka a pe: "ęnikęni ti o jęwọ" ęṣę rẹ̀ "ti o si kọ̀ ọ silę yio ri ãnu" (Owe 28:13). A ka a pe: "Bi awa ba nrin ninu imọlę, bi

on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ni idapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ Rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johannu 1:7). Eyi ni eto Ọlọrun fun igbala gbogbo eniyan. Eyi ni ọna a ti bọ́ kuro ninu iparun ti o n bọ̀ wá sori ayé.

Ọna ati là ṣi silẹ fun gbogbo eniyan, ṣugbọn kiki awọn ti o gba Ọlọrun gbọ́ ni a o gbala. "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johannu 3:16). "A ti da ẹniti kò gbà a gbọ́ lẹjọ na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bibi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ́" (Johannu 3:18). Awọn miiran wà ti ko gba Ọrọ Ọlọrun gbọ́ lonii. Awọn miiran wi pe awọn gba Bibeli gbọ́ ṣugbọn wọn ko gbọran si Ọlọrun, wọn ko si mura lati lọ si Ọrun.

Awọn miiran wa lonii ti ki i waasu gbogbo Bibeli; gẹgẹ bi apẹẹrẹ, wọn wi pe ko ṣe danindanin lati gbé igbesi-ayé pipé ati mimọ́. Ṣugbọn Bibeli wi pe, "Ẹ mã lepa alafia pẹlu enia gbogbo, ati iwa mimọ́, li aisi eyini, kò si ẹniti yio ri Oluwa" (Heberu 12:14). Gẹgẹ bi Noa ti ṣe "gẹgẹ bi gbogbo eyiti Ọlọrun paṣẹ fun u," bẹẹ ni a ni lati gbọran si Ọlọrun ninu ohun gbogbo.

Ihinrere Jesu Kristi ni abá ati là fun wa. Oun ni Ọkọ̀ wa ati ireti wa kan ṣoṣo. Ẹ jẹ ki a fi Ọkọ̀ ti wa wé ti Noa. Jesu wi pe, "Emi ni ilẹkun: bi ẹnikan ba ba ọdọ mi wọle, on li a o gbà là" (Johannu 10:9). Ọkọ̀ Noa ni ilẹkun ẹyọ kan pere. Ọkọ̀ Noa ni ipele mẹta, Bibeli si kọ́ ni pe iriri mẹta ni o wà ninu Ihinrere: igbala, isọdimimọ ati ifi Ẹmi-Mimọ wọ ni.

"Nipa igbagbọ́ ni Noa, nigbati Ọlọrun kilọ ohun ti a koi ti iri fun u, o bẹru Ọlọrun, o si kàn ọkọ̀ fun igbala ile rẹ̀" (Heberu 11:7). Awa naa ni lati pese ayé wa silẹ, ki a ba le sá kuro ninu iparun nla eyi ti n bọ̀. A ni lati gbadura, ki a si jẹ oloootọ si Ọlọrun. A ni lati gbọran ki a ba le ṣe iṣẹ igbala wa yọri pẹlu ibẹru ati iwariri, gẹgẹ bi Paulu ti kọwe rẹ̀ si awọn ara Filippi (Filippi 2:12).

**Ilẹkun ti a Ti Tì**

Ni ọjọ kan Ọlọrun sọ fun Noa lati bọ́ sinu ọkọ̀ naa, pẹlu awọn ẹranko. Nigba ti Noa ati awọn ara ile rẹ̀ ati awọn ẹranko wà ni alaafia ninu ọkọ, Ọlọrun sé ilẹkun pa. Ninu Bibeli a kilọ fun wa lati tete mura silẹ ni akoko. "Ẹ wá OLUWA nigbati ẹ le ri i, ẹ pè e, nigbati o wà nitosi" (Isaiah 55:6). Akoko kan n bọ̀ nigba ti ilẹkun igbala yoo tì, ko si si ẹni kan ti yoo le ṣi i. (Ka Ifihan 3:7).

**O Ti Pẹ́ Jù**

Nigba ti omi bẹrẹ si kún, lai ṣe aniani ọpọlọpọ eniyan gba Noa gbọ́. Ṣugbọn akoko ti pẹ́ jù lati wọ inu ọkọ̀. Oluwa ti ti ilẹkun. Noa wà ni alaafia ninu ọkọ̀, ṣugbọn gẹrẹ lẹyin ti ilẹkun tì ni ojo ti n pa awọn eniyan, wọn o si ṣegbe nipa rírì. O ti pẹ́ jù ki wọn to gbagbọ́!

Fun ogoji ọsan ati ogoji oru ni ikun-omi fi n pọ si i. Gbogbo ẹda alaaye ni o parun – ayafi Noa, ẹbi rẹ ati awọn ẹranko inu ọkọ. Lẹhin ọjọ pupọ ikun-omi naa gbẹ. Awọn igi bẹrẹ si ruwe. Ṣugbọn Noa duro sinu ọkọ titi Ọlọrun fi sọ fun un lati jade.

**Ami**

Lẹyin ti Noa, awọn ẹbi rẹ̀ ati awọn ẹranko ti inu ọkọ jade ti wọn si ti tun wà ni alaafia lori ilẹ gbigbẹ, Noa tẹ́ pẹpẹ fun Ọlọrun. Oluwa ṣe ileri pe omi ki yoo tun pa ẹda alaaye gbogbo run mọ́ lori ilẹ. O fi edidi di ileri Rẹ̀ pẹlu ami oṣumare. Nigbakigba ti a ba ri oṣumare o n rán awọn eniyan leti pe Ọlọrun ko tun ni rán iru ikún-omi bẹẹ wa mọ́ lae. Ṣugbọn o yẹ ki oṣumare tun maa rán wa leti pe lọjọ kan idajọ irú miiran yoo wá sori ayé, gbogbo awọn ti o si wà ninu rẹ̀ yoo si jona luuluu (2 Peteru 3:10). "Njẹ bi gbogbo nkan wọnyi yio ti yọ́ nì, irú enia wo li ẹnyin iba jẹ ninu ìwa mimọ́ gbogbo ati ìwa-bi-Ọlọrun?" (2 Peteru 3:11).

## AWỌN IBEERE

1 Irú eniyan wo ni Noa?

2 Bawo ni o ṣe yatọ si awọn ẹlomiran ti wọn wà laye ni akoko kan naa?

3 Ki ni ṣe ti Noa fi kan ọkọ̀?

4 Awọn wo ni o wà ni ailewu ninu ọkọ̀ naa?

5 Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi rán ikún-omi naa?

6 Ki ni ṣẹlẹ nigba ti Ọlọrun rán ikún-omi naa?

7 O pẹ́ to akoko wo ti òjo fi rọ̀?

8 Ipele meloo ni o wà ninu ọkọ̀ naa?

9 Nigba wo ni Noa jade ninu ọkọ̀ naa?